**Owe**

Adię iba l'ọkọ, iba l'atitan se ẹkan. Imado iba ṣe bi ọdẹ a ba'to jọ. Ẹru iba ſ'ọba, enia ko ba ti ku ọkan.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Asoje**

Enia ma jiki t'enia sunwọn, t'eni ma sunwọn ko ni gbọ. Apa ọmọde ko le ka igi Ọṣe, yio ma doyika.

OL. XIII No 681 LAGOS, SATURDAY MAY 12, — MAY 19, 1961. KỌBỌ MEJI (2D)


## EJO AWO ELEGBA NI ILOGBO DI ERUJEJE FUN ELERI

EKO— Ninu Kotu Yaba ni ọkunrin Adahunṣe kan, ti o njẹ George Oseji sọ fun adajọ wipe lẹhin ti ọjọ ti oru di ẹrujẹjẹ fun on de po ti on kole jeun fun ọjọ mẹta tẹkọ'a, ni on to lọ si Ṣọbu awọn ọlọpa lọ sọ gbogbo nkan ti o ti ṣẹlẹ fun wọn, bi awọn ọpọ enia ti ṣe ki enia kan mọ'ẹ, ti nwọn gbe wọ'nu ile kan ti o nkegbe ni oru ọjọ na.

Awọn ti Oseji njẹ i tako ni awọn enia mokan-din-logun ti nwọn mba ṣẹ egbẹ olọnkun ti Oriṣa Ẹlẹgbẹ. Awọn ni:- Reski Lawal, Reski Kadiri, Moses Ọlọjede, Yesufu Folọl, Braimoh Abudu, Rabiu Awotunde, L t n Gewo, S nsi A[illegible], Lasis Akinobi, Fasasi Lawal, Olu b[illegible], Momodu L[illegible], B[illegible] [illegible], Bell[illegible] Faro, L[illegible] Oshodi, Sule Yesufu, Jimọ Buraimo Abbu Lawal ati R h mi Olokun.

George Oseji sọ ninu eri rẹ wipe ni atẹ ọjọ kan ninu osu April, bi on ti nlọ si Ilogbo l'ona Apapa, ni Opopo Oko bir[illegible], on ri ẹ ik n ti o gun basikulu niwaju on, o to dede agogo mẹwa abọ alẹ. Lojiji ni awọn ọpọ enia rọ lu ẹnito gun basikulu na, nwọn ki mọlẹ, nwọn si gbe wọ'nu ile kan lọ pẹlu bi o ti nkegbe lede loo bayi: Ṣinẹke ! Ṣinẹke !! Ṣinẹke !!!

Ẹnikeji ti o tun jẹri ni Ọgbẹni Paul Bello, ti iṣe ọga ninu ile iṣẹ iṣegun ijọba ni Oshodi, sọ wipe ni

ọjọ ti on lọ si Ilogbo on ri ẹjẹ enia lara nkan ninu ile Ẹlẹgba. O sọ wipe on si ha awọn ẹjẹ ti on ri lara nkan, ti on yẹ wo ti o jọ ẹjẹ enia.

O tun sọ wipe ni ọjọ kejila osu April ni nwọn re on lọ wa inu ile kan ni N0. 12, Hoto Dawodu ati N0. 8, Opopo Ọpẹolu ni Ilogbo, nibẹ ni'on ti ri awọn afihan obe ati igba ti eje wa lara wọn

Fun nkan bi wakati kan abọ ni Loya, Ọgbeni Adewale Thompson pelu Ọgbeni Bello fi se ariyan-yan lori ẹjẹ ti nwon ri, Ogbeni Tompson si sọ wipe awon yio pe Ogbogi Onişegun ti yio wa fihhan wipe awon ẹjẹ na ki iṣe ti enia.

Kini abayori ẹniti nwọn sọ wipe nwọn gbe wọ inu ile nipa, ti nwọn si lu, ti o nkigbe, Ọlọrun - Ọlọrun !!. Ko si ẹniti o le sọ nipa ọrọ nla yi niwaju adajọ-ibere Kotu ni wipe njẹ otitọ ni ọrọ na tabi nwọn pa okunrin na ni.

Ọga Ọlọpa inu Ọgbẹni John Izoiswe sọ wipe on tu ile na wo. on ko ri ẹnikọkan nibẹ a ko si tun ri ọkunrin na rara. Awọn enia mẹta ti o tun jẹri sọ irufẹ ohun ti oju wọn ri nigbati awọn ba fẹ ṣe ọdun Ẹlẹgba, nipa ikilọ pe awọn ko gbọdọ jade lẹhin agogo mẹsan ale ati pe ki awọn pa ina ile fun ọjọ meje. Awọn si nilati da 4/6 fun ẹgbẹ Ẹlẹgba na.

Nwọn si mba ẹjọ na lọ.

## Olotu Ijoba Ilu Saro Gbalejo



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni Olotu Ijọba Omi ira ti ilu Saro Ọlọla Sir Milton Margai, nigbati o ngba Eni-ọla Ọmọba Oloye Duke ti'lu Ken, ti o wa s'oju fun Alaiyeluwa Ọba obinrin Elizabeth Keji ni alejo ni ibudo ọkọ ofurufu ni Waterloo nilu Saro, ni asiko ti ilu Saro gb'ominira laipe yi.

Ilu Saro gb'ominira ni ọjọ keta-din-logbo osu April, 1961, ilu na si ni o je omo egbe titun nis'siyi ninu awon ilu Ominira ti o mba Geẹsi epo.

# OGBENI AJOSE-ADEOGUN FESI FUN AKINJIDE

Nisisiyi ti Ogbeni Akinjide ko lati tun oro ti o so ni ile igbimo Asofin so ni gbangba gegebi ileri re, emi setan nisisiyi lati se alaye oro na fun gbogbo enia lati le mo otito ati ododo oro na.

GBANGBA D'EKUN

O yani lenu pupo lati gbo pe Ogbeni Akinjide wipe ki a jebi oro na pe-ri be, ... [illegible] ... ni Ogbeni Aki[illegible] ...gb. wole.

ORO ILE L. E. D. B

Ohun meji pataki ni o wa ninu afisun oro ti. ekini, ohun ... gbo-gbo-gbo, o kan ... ile o kan alejo, okan onise ola, o si kan awon Oselu paapa ati enyin Onlwe irohin.

Gbogbo ohun ti Ogbeni Akinjide so si ... gbogbo iwe irohin ewe ati oro gbohungbohun, bi o ba je be, ise gidi gidi ni o se fun ilu ... ti fun ilosiwaju wa gegebi orile-ede, sugbon, ohun wonyi ha jebe bi ?

IWA OMOLUWABI

Nje ohun ti o tona ni ki enikan dide ni ile igbimo lati se atako elegbe re nigbati o mo daju wipe oluware koni anfani lati da on lohun tabi ti oluware kosi ni itosi, Gbogbo wa ni o mo wipe irufe iwa bayi ko ye omoluwabi enia.

Ogbeni kan ti npe ni P. E. Ekanem se itokasi eyi, sugbon kori eni gbe le se Ogbeni Akinjide kan nse atako re lo ni, pelu bi Alase ilu igbimo ti mu ... ona to. Mo gbo wipe Ogbeni P. E. Ekanem ki nse ise amofin ninu ile igbimo, o je ohun ti o ti ni loju wipe onise amofin elegbe mi ni yio je eniti o nse ibaje si ohun abiyi bayi.

O ye ki Olotu ijoba wa Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa ati awon isongbe re gbe oro yi wo dara-dara nitoripe ohun yi le kan iwo paapa tabi enikeni ti ko ni anfan lati joko si ile igbimo asofin lehin wa ola.

ILE NO. 610 ATI 611

Ile meji ti o wa ni oke iwe yi nikansoso ni o le ... [illegible] ... ile ... nso'o si ... L. E. D B. ... [illegible] ... (£12 : 15 : -) ni owo re lodun.

Ile ti o wa ni Opopo Massey. Ogbeni R. A. Doherty ti o nse adajo ni Ibadan ni o ni ile yi. Egbon mi agba si ni o haya ibe gbe, owo ososu ni o nsan fun ile yi.

ILE MEJI NI ITIRE

Ile meji ti o wa ni Itire ti Ogbeni Akinjide pe ni t'emi, ko nse be, ti Iyafin mi ni, ati odun 1957 ni o ti kowe fun ile yi gegebi gbogbo awon enia ti nse ko re, ni odun keta lehin eyi ni a fun ni ile na.



T. O. S. BENSON

Ogbeni Iyafin mi je ni ise re, owo osu re si jeju to fun lati le ni ile tire. Bi a ba ye owo osu temi a'i eyiti Iyafin mi ngba papo, eto ni ki awa mejeji 'e ni ile lori, gegebi eyiti ori re pe. Bawo ni Igunti sepa lori ti Obo ko pa.

Alaye wonyi fihan wipe Ogbeni Akinjide ko otito oro wonyi han enyin elegbe re ni ile igbimo Asofin, o si ti jeki'e sina.



OLOYE OKOTIE-EBOH

ILE NO. 457 APAPA

Emi ko mo eniti o ni ile yi, sugbon ninu iwe awon L. E. D. B Ogbeni kan ti nwon npe ni Freeman ni ilu Ibadan ni o ni, nko mo Ogbeni Freeman yi boya on paapa ko mo mi, nko le so !

ILE NO. 233 APAPA.

Ore mi kan ni oni ile yi, ninu odun 1950 ni o ti kowe re, ninu odun yi ewe, emi ati Iyafin mi wa pesepese nilu Oyinbo. Ore si ore ni nwon fi gbe ile yi fun emi ati Iyafin mi nigbati a pada de lati ilu Oyinbo, ti ako ri ile gbe, yiya ni a ya owo ko ile na a si nsan owo ti a ya pelu ele re nibiti ... ti ya.

ILE NO. 451 APAPA.

Ti egbon mi agba ni ile yi, oruko re si nje Olayinka, Olatunji ni oruko ti emi, bi e ba si ye won iwe ile yi wo, Olayinka ni e o ba nibe. Egbon mi dagba to omo odun mejidinlogoji, o si ni ise le lowo.

Bi Iyafin mi ti gba ile beni Ogbeni Benson Oloye Okotie-Eboh ati Oba Adeniji Adele paapa gba.

Ejo ti emi re o, enyin ara' eni ni o kan l'oni boya o le kan iwo paapa l' ola!

## Jamba Oko Ofurufu

JAMBA oko ofurufu ti a gbo wipe o sele ni eyiti enia mejidinlogorin ti o mbe ninu re padanu emi won.

Oko awon Faransa ni oko ofurufu na, ninu okun yanrin Sahara ni nwon ti ri oko na nibiti o ybe bale si. Ni ... ojo Tuesday ni oko na si nlu Brazzaville ti o si di awati.

Nwon so wipe nigbati oko na ti de Okun yanrin Sahara ni nwon ti gburo re mo.

## Ojilile Pania Meji-le-logun

PAKISTAN Ojilile ti o ja ni iha Ila-orun ilu Pakistani ni ojo Tuesday pa enia meji-le-logun, o si se bi adojo eni l'ese.

Opolopo ile ni o wo lule, awon oko ri sinu omi, aji gba omiran da soke. Ohu awon igi t'egbo-t'egbo, o si ngbe won fo loju orun.

Ojilile na si orule ile Gomina iha Ila-orun ilu Pakistani Ogagun Mohammed Azan Khan. Awon oloko ofururu da ise duro fun odidi ojo kan.

O le ni egbeje enia ti ojilile pa ni ilu kanna yi ni osu October to koja.

E Ma Ka Iwe Irohin Eleti - OFe Fun Irohin Aladun

# JAMBA INA SELE NILU EKO

EKO—Ina nla kan ti o jo ni Opopo Asani n'oju ọjọ ọs, ti o koja yi sọ enia ti o le ni ogọrun di a;a i ile leri.

Alhaji Mustafa ti o gbe ile kẹta ni Opopo Asani sọ wipe on ati awọ ẹbi on ti wọle sun nikan bi agogo mọ ana abọ, n'gbati anwo ina ta ni awọn sare bo s'ode. Awọn iyara mejọ ti oa ngbe ninu ile na jona kanlẹ ra-rau

Lọwọ jamba ina ati jamba omi, Olu a rete gba wa.

## Nwon Fe Ba Tshombe Sejo

COQUILHATVILL— Irohin ti a gbọ lati ilu ti awọn Ototu ijọba ilẹ ijọg ọn Kongo lọ ṣe ipade, lati le f'ohun sọkan pari rogbodiyan ilẹ wọn, ti ọkunrin alag ara ti nwọn npe ni Tshombe ti ilẹ Katanga binu jade kuro ni ipade, eyiti o fa o fa sababi mimu ti nwọn yar lọ ramu ti nwọn ko jẹki o wọkọ Ofurufu pada silu rẹ.

A t n gbọ wipe nwọn yio ba Tshombe Olotu ijọba Katanga na ṣe ẹjọ lori ẹsun mẹrin pataki ti o ti fi dẹṣẹ si ijọba arin ilẹ Kongo.

Ọgbẹni Bombolo ni o ka ẹsun mẹrẹrin na si ọrun Tshombe, Ọga'gun agba ọkunrin ti wọn npe ni Joseph Mobutu wa ni ẹgbẹ rẹ nigbati o nka awọn ẹsun na.

1. Pipa ti o pa awọn enia ara Faluba niha Iw,-orun Katanga.
2. O ngba ẹkọ awọn ilu Okere fi ẹ'ẹtẹ si ijọba arin ilẹ Kongo
3. O nfi agbara ko ẹrun ẹra inu Ọ'ọ ofurufu, ati owo ti iṣe ti ijọba arin ilẹ Kongo nigbati o da ilẹ Katanga fun ri ijọba Onile ra l'ọdun tokọja
4. O ṣe owo adamodi nitori riṣe o l e ina owo iyato fun ilẹ Katanga. O tilẹ sọ wipe adọtẹ silẹ enia ni Tshombe.

A tun gbọ pe awọn ti bere si gba ohun ija kuro lọwọ awọn omoogun Katanga niha Iwo-orun ar. Nwọn so pe yio to iwọn omo ilẹ Gesi ati awọn enia funfun ti ilẹ iha Gusu (South Afrika bi ọgọrun ti yio fara gba

Opolopo awọn omo ogun egbẹ ajẹoba e (U N) ni nwọn ti nko lọ sile Katanga, arope o to egbarin omo ogun ni'sisiyi

M Munongo, alagbara okunrin ti o wa nile Katanga so wipe bi nwọn ba lọ agbara fun awọn, pelu bi Tshombe ko ti si nile on ko ni juwo sile

*Iṣẹ to dara!*

Iṣẹ to dara pẹlu owo ọya ti
kò tàsé lo nfun ènia ni iyì ati
igbesi aiye to layọ̀.
*O lé ni ẹgbã mẹsan ara Nigeria*
to mbẹ lẹnu iṣẹ to fẹsẹmulẹ labẹ

**THE UNITED AFRICA COMPANY**

THE UNITED AFRICA COMPANY
OF NIGERIA LIMITED

## Dokita Udoma Di Adajo Agba

EKO— Ninu ile Ọba ni ojo Monday ose yi ni Olola nla Dokita Nnamdi Azikiwe, P. C. Gomina Gbogbogbo ilẹ Nigeria fi Dokita Egbert Udo Udoma ati Ọgbeni George Sodeinde Sowemimo bura si ipo Adajọ Agba ti kotu giga ilu Eko

Nibi ayeye rampe na Adajo Agba Kotu giga ilu Eko, Sir Clement Nageon de Lestan ati Ọgbeni V. Crad. Ọg akowe Kotu wa nibẹ.

ELETI—OFE

ANUWON KO SE WO ...

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
28, Kosọkọ Street Lagos. "ELETI-OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. XII. NO. 689. SATURDAY MAY — 12 MAY 19, 19..

# IREPO NI AGBARA

Gbolohun akọle oke wosika wa ọsẹ ni a fi ṣe ẹsin aṣaro ọrọ wa lati le fi se aiaye fun ẹnyin ọkawe wa lori iṣe ribiribi ti awọn Olotu ijọba wa, ati gbogbo awọn Olotu ijọba ilẹ enia dudu ti o ti bọ ajaga sile kuro labẹ itọju ilu aleji, ti o t. di Ominira ara wọn lọ se nina ipade ti nwọn ... lowọlọwọ yi nilu Monrovia ti o fẹ aṣiwaju ilẹ enia dudu ti o kọkọ gbominira.

Kosi ifọkanbalẹ fun ilu ti ko ni irẹpọ pẹlu awọn ilu miran, fuu anfani ... o daju, gẹgẹbi ede oyinbo ti awọn olukọ wa fi kọ wa bayi :- "United we stand devided we fail", eyiti a le tumọ si bayi ni ede Yoruba, "Irẹpọ ... e enia duro, aisi irẹpọ ni iṣubu enia wa".

Eyi si ni ọrọ pataki ti Alakoso Ilẹ Liberia-Ọgbẹni William Tubman fi si ipade nla na wipe gbogbo ilẹ enia dudu ti o ti gb'ominira ni yio duro ṣinṣin lẹhin ara wọn nibikibi ni agbaiye.

Nitorina, o tọ o si yẹ ki gbogbo wa wa ninu irẹpọ fun anfani alafia ara wa. Nitori irẹpọ ni agbara wa.

# KIN NJE ODUN GBEIYEFO

ko le so nkanka... mọ ju pe, o nsọ on to ti, irọ gba l'a ye ji niyẹn, ko na dara pupọ bi Buroda na ba kuku netan fun ... a pe ou ko ni kudi ọwọ ka kuku mọ arun ti o nṣe ... awo.

A tun wa bi ẹdrasirin yi pe, iru aso wo ni iwọ rope ... tọ nina lati wọ fi gbe iyawo, o ni asọ kan ti nwọn npe ni santọnu ni o tọ sunu, ẹ ko wa ri arun ti o ... Ọgbẹni o ... awọn aso to ri ko tọ suna pẹlu asọ ti o ni o to suna nwọnyi on, ewo lo ba dara wayi o, bi a tilẹ sọrọ kan mọ, mọnnọ ti mọ yin.

Ẹko wa ri gbangba pe, ẹnu wa yi la fi nfa nkankinkan wa si ori ara wa, awọn ẹlomiran a ma tọ pe ọjọ kan lo da lati gbe iyawo, ọjọ kan ko dara ninu, gbogbo Ọjọ ti Oluwa da ewo ni ko dara ninu rẹ, tabi iwọ to ni ọjọ kan ko dara, nijọ wo lo ti odo Ọlọrun bọ wa, ti o si sọ fun ọ pe niun gbogbo ọjọ ti on da, ọjọ kan lo tọ sura, ikan ri ko tọ suna, tabi rinu iwe wo la le ri ninu Bibeli pe ijọ kan ni Oluwa ya sọtọ lati gbe iyawo, a si mọ pe Jesu papa l, si ibi iyawo ri nijba Aiye rẹ.

( Wo voku lojo iwe karun )

# NWON SE IPADE LAIGBAWE ASE

LAFIA - Awọn enia mọkan-din-logun ti nwọn jẹ ọmọ ẹgbẹ NEPU ni Alkali kotu Lafia da lẹbi wipe nwọn ṣe ipade laigbawo aṣẹ. Nwọn rojọ mọ wọn lẹsọ pe wọn se ipade iselu ni Barakin Abdullahi ni ọjọ kẹta-din-logun oṣu April, nigbati ọlọpa kan lọ lere iwe aṣẹ ti nwọn gba nwọ mu ọlọpa ra, nwọn si ... mọ i'e Aṣ'waju wọn, lẹhinna, nwọn lu ki nwọn to da silẹ. Orukọ Ọlọpa na nje Afrikia. Ẹniti o jẹ olori abule wọn ti o lọ lati gba ọlọpa na si fi f'ara gba tirẹ bakanna.

Alikali ni ki o lọ san owo ponna marun to fi ponu mẹdogbọn ati ẹwọn lati osu meji de osu mejidin-logun fun ṣise ipade iselu laigbawe asẹ.

Awọn marun ninu wọn ati ọmọde kan ni nwọn kọ idajọ na, ti nwọn si gbe yi lọ si kotu arotunro ni nwọn da silẹ.

# AWON ALAFOWOYA OTO NILU OYINBO



Awọn Oluko mejì ti a nwo ninu aworan yi ni Asoju ilu Ila-orun Afrika (East Africa) nibẹ larin won nibiti nwon ti ye awon aworan alafowoya wo kiri nilu Oyinbo. Awon mejeji jẹ Oluko aworan alafowoya nilẹ won, Ila-orun Afrika.

# OLUKONI L'ERE IDARAYA



Aworan ti a nwo yi niti Ogbeni Jim Alford, ti o mu omo kan lapa dani yi, o ti nko won ni ere idaraya nilu Wales fun odun mejila.

Ninu osu March ni agbo wipe Alford yio ti bere ise akoni l'ere idaraya nile Apapoje ti Rhodesia ati Nyasaland.

## Kini Nje Odun Gbeiyefo

(O bere loju ewe keria)

In... yie si dya ti Imale k... ba le ... f... we pe ... ie ... Mo o-du ya si ... to ... fun ... olo igbeyawo ati idi ohun ti awon ... lyoku ko te d...ra enyin Onibulu ... e o je ... si re, da...dera ni ... gbo ... Ise ti Olorun se titi fi ojo kefa, ko to wa simi ni ojo keje.

## Chike Obi Faragbalamo

EKO— Ni ojo Atalata (Tuesday) ni Kotu giga ilu Eko se idajo fun Dokita Chike Obi lori esun wipe o npiniwo ise si ijoba fun awon enia.

Adajo so wipe on yio se idajo niba ranpe fun Chike Obi nitoripe o ... o fun ilu ati ailabawon iwa re lati ehin wa.

Adajo sa konko ogorun ponun fun ni sisan tabi ewon osu meta.






## Gomina Gbogbo-gbo Seranlowo Silewe Odi

IBADAN — Olola nla Dokita Nnamdi Azikiwe, Gomina Gbogbogbo ile Nigeria fi Ogun ponun (£20) se iranlowo fun ilewe awon aditi ati Odi nilu Ibadan.

Olola Sir Adesoji Aderemi Gomina ipinle Iwo-orun fi Ponun mewa sile mewa (£10. 10. 0) se iranlowo fun ilewe na.

Awon to se iranlowo fun ilewe awon aditi ati odi nilu Ibadan lati ikede itoro owo ti nwon se nisu odun 1961, yi ni Oba I. . Akiyele Olubadan tilu Ibadan, Poun medogbon.

| | £ | s | d |
|---|---|---|---|
| Ogbeni N. Al'zakhem | 25. | 0 | |
| Oloye A. O. Makanjuola | 10. | 10 | 0 |
| St ... nnes School | 5. | 9. | 2 |
| A. J. A. Olufawo | 2 | 2. | 0 |
| C. O. Phillips | 2. | 2. | 0 |
| D. A. R. Alexande | 2. | 0. | 0 |
| J. Oke | | 10 | |

## Eleti ofe daraba

## Isowopo Awon Ajo Elesin Isese

Isowopo awon Ajo Elesin Isese tabi Ibile Eko ilu dudu ti oruko re nje "The Ancient Religious Societies of African Descendants Association" (Incorporated in Nigeria), yio se Ipade gbogbo-gbo ti osu-mẹta ta ni ojo Aiku (Sunday) ti ise ojo kerinla osu yi (May 14) ni agogo mewa owuro (10 a.m.) ni Ile Oloye Fa bemi Ajanaku Araba, Ile Eko, 55, Okepopo Street, Eko. Ki esi gbogbo awon Ajo tabi Ile Elesin Isese tabi Ibile pe sibe.

Mo duro ...
Abiodun B... run
Akowe

## Kini Nje Odun Gbeiyefo

Lati Owo Aiwiye

Ko dede ti a fi sa bere wo oke yi, a ma ngbo ti opolopo awon enia ma npe odun kan ni odun Gbeiyefo eyi ti awa npe ni Leap year, awon enia a nsaso fun ri pe odun Leap year gege bi odun 1928 tabi gbogbo odun ti o ba je Leap year ki nse odun rere ati pe iku si po ninu re, awawi l'awa ri eyi si ti pe isokuso lo si je, nje enyin Onibukun ninu iwe we ninu Bibeli li a gbe ko nipe odun yi ki nse odun rere, odun wo li ha wa ti ki nse odun rere, laisi asi ani ohunkohun ti enia ba fi enu ara re fa lo ma ri, enikan nse nikan ko si nbe.

Nje mo fe bere lowo awon onisokuso wonyi pe odun 1918 ha nse odun Leap year ti Ajakale Arun fe run gbogbo Aiye tan, tabi odun 1923 ha nse odun Leap year, ti awon odo ti o sele gbe iyawo nin ngtana ku lo bere re. Oluwa je ki iru iku be ma jina si rawon, e o pe ko si odun ti nkan ko le ba enia, ohunkohun ti o ba si ba enia, e je ki gbe rere idupe.

E ye fi isokuso eyin ja awon eni to fe gbe iyawo l'eya, Oluwa ko ni je ki won ri ikusi, bi isokuso ti po laiye to, awon enia miran nso fun elegbe won ti o npalemo ati gbe iyawo pe, aso ti a npe ni Gray ko dara lati fi gbe iyawo ati aso bi Black over trousering, enyin gbajumo ninu aso kini tun dara lati fi gbe iyawo ti morning Coat la ti yo ju awon aso wonyi lo, a si tere pe kini gbajumo ti ki o to ri awon aso wonyi ko dara.

## AWAMOTO TI KO BIKITA

THE FAULTY DRIVER




Awon Awamoto ti ko bikita, ko ns'akiyesi Opopo ona, o le kolu moto miran ti o ie eni, afije ran lese. E, sora.

## IJA BE SILE LARIN EGBE MEJI

Kaduna — Awon egbe Olomi ati egbe NEPU ni ngan ija be sile larin won ni ojo Satide nigbati awon omo egbe Olomi (N.P.C.) ti ibiti awon gbe nka bo bo, ti awon si nkorin eLu si omo egbe NEPU, ati pelu gbogbo oro enu won ti awon nso pe awon lo ni Kaduna, awon ko tile padanu ijoko ilu Kaduna nikan, gbogbo ijoko pinle Ariwa, eyo kansoso ni nwon ri ri.

Nigbana ni ori awon omo egbe NEPU gbona, ni ija nla ba fi bere, awon enia ti nwon ko lo si sobu awon olopa ologoje ninu awon omo egbe mejeji.

Mala Aminu Kano ti ise ori egbe NEPU ti so wipe awon igbati egbe Olomi (N.P.C.) ba ti nse orisirisi jamba lati fi segun alatako, be a ni yio ma fi ese ara re. O ni eyi ni lati je be nitoripe awon oro ti nwon sese ndide ko ni gba won laye kekere ni ilu Ariwa.

## ALHAJI SIR AHMADU BELLO GBE IJOBA ARIWA DURO

KADUNA - Kesi ayipada to dati ara ninu ijoba titun ti Olotu ijoba Ariwa se eto re lehin ti abayori ibo ti nwon di ti jade tan, ti o si je wipe awon egbe Olomi (N. P. C) ti o ti Al se ijoba ilu Ariwa na ni o tun fo'e fun u.

Awon ti Olotu ijoba yan si ipo Alakoso ijoba ile Ariwa niwon i: Eni akoko ni Olotu ijoba, Alhaji Sir Ahmadu Bello Awon Minista fun orisirisi ise ijoba ni Alhaji Mustafa Mangano, ise agbe Alhaji Isa Kaita, Madawakin Katsina, Ise eko, Iwe, Mallam Mu'assu Lamido, Ise itoju awon eran osin ati igbo, Alhaji Alhu Makaman Bida, Alase inawo, Alhaji Ahman Galadiman Pategi, Ise Ilera ilu; Alhaji Muhammadu Kabir Ciroman Katagum, Ise ilu Alhaji Ibrahim Bin

(Wo yoku loju ewe keje)

NIGBATI OJA KO BA TA, TI ENITI O NRA OJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI SELE FA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONISOWO LE SE TI OJA RE YIO FI MA TA BI ISU AKARA GBIGBONA.

E Polowo Oja Yin

Sinu Iwe Irohin

Eleti-Ofe

E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE L'OSOSE.

# ALHAJI SIR AHMADU BELLO GBE IJOBA ARIWA DURO

(O bere loju ewe kefa)

Ozirohin Ijoba Mallam Ibrahim Musa Gashash, Işe ile, Ogbeni Michael Audu Baba Işe idarays ati isowopọ; Alhaji Bashar, Wamban Daura, Işe ijọba ibile, Alhaji Shehu Usman, Galadiman Maska, Işe Owo ati Işe owo, Ogbeni Abba Olokpo, Işe ilu ati Malam Sale Gaya, Ile işe ijoba.



Awon Minisita ti ko ni ile işe niwonyi : Sir Abubakar, Sultan, ilu Şokoto, Alhaji Usman Nagogo, Oba ilu Katsina Malam Sulu Gambari, Oba ilu Ilorin ati Malam Ali Obaje, Atta ilu Igala.

Boya bi Olotu ijoba, Alhaji Sir Ahmadu Bello ba ti irin ajo re de, eyiti yio bere ni ojo kerin-dinlogun oşu May yi, ni yio to şe eto yoku.

## Polowo Oja Re Sinu
## IWE ELETI - OFE

# E MASE FOMI SOFO.




**E wo aworan awon Omode ti nwon yi ero omi sile ti nwon nsere titi ti koroba fi kun akunya sile.**

**E kilo fun awon omo nyin.**

# OBA ILU EKO



Aworan Alaiyeluwa Oba Adeniji Adele Keji, tilu Eko, ti Ogbeni Ajose-Adeogun soro ... nipa alaye ... re ... oju ewe keji ... Irohin ...

# EJO IJA ŌTE NI KADUNA

KADUNA - ..inu Ko.u itile t.l u Kaun n i o j Alaruba (Wednesday) ni ebia meta-di..-logu.. r'.jo w pe awon k. si nibi ja ti nwon ja ni Tudu Wada n.-nu ęse yi.

Qkan .inn w..n ti orukọ r. nje Garuba Jakoto sọ wipe ṛẹlu ibọn ìẹhin n. awọn ọlọpa fi ti on w ọ inu mọto wọn.

A ti ni ero wipe ejọ na yio parı tẹlẹ ni kia, şugbọn awọn yoku ni nwọn ma t.n şe ẹjọ b i b a wọn ọl pa ja.

## Baba Ko Jebi If'omo Sofa Kowo

Abeokut – Ejọ Ọ..bẹni Raji Apata t i w ọ n fi ẹsun ẹsun wipe o fi ọmọ rẹ Ọkunrin bi ọmọ ọdun mẹwa sọfai kowo pọnun mẹta-l -ladọta ati şile mejila (£53: 12: 0) ni adajọ d a silẹ wipe k o j.bi ni ọjọ Alafuba (Wednesday) ọsẹ .i

Adajọ Ọgbẹni C. A. Piper sọ wipe awọn ọlọpa ko fihan pe iwa ibajẹ ti şẹlẹ. Ẹsun ow o-ẹru ko le mu duro gẹgẹbi ohun ti o le mu baba na

Nitorina, ki o ma lọ ni alafia.

## Oloye Akintola Pe Anyiam Lejo

Ejo ti Oloye S.L. Akintola, Olotu ijoba Iwo-orun pe Oloye .nyiam lori iwe kan ti o pe "Awon enia pataki ilẹ Nigeria" t ı



Oloye Anyiam se t. O..ye Akintola so p..o ma awon enia ẹe'ye-meji npaawon obi on, ni nwon fi ejo na si ojo karun oşu June, 1961, ni Kotu gigaı tilu Eko.


# FIAT 1100
## New Model

For
HIGH PERFORMANCE
SPEED
AND
COMFORT



The new improved version of the 1100 FIATS have more modern lines, twin carburettors, for speeds over 80 m. p. h. sw'velling ventipanes on front door for greater ventilation and now costs less.

| PRICE EX LAGOS | PRICE EX TURIN |
|---|---|
| EXPORT £625 | EXPORT £398 |
| SPECIAL £685 | SPECIAL £450 |

Available from

## Leventis Motors Ltd.

LAGOS (EB) IBADAN, KANO, JOS, KADUNA, PORT HARCOURT, ABA.
Sub-Distributors:
ARMEL'S TRANSPORT LIMITED
BENIN-CITY & ONITSHA.


## Kosi Owo Lori Iyawo Nile India

Eyi ha le işẹ bi A b.. wipe a w ọ n Igbimọ Aşof.n ilẹ India ti panupọ lati şe ofin • pe enikeni ko gbodo gba owo lori obiuriu mo. Iyen ni o w o idana o..obinrin nilẹ India.

Eniti o ba kolu ofin yi, y i o fi ẹwon o ş u mefa şe if.je ati owo sisan bi ponun mẹdogbon-din-nirinwo (£376 si ko..u.

# T'OKO TIYAWO NINU APOTI ERI NI KOTU

ABA - Ad.jọ fi riro ẹ'ọ ẹsun oie j i j a ti nwọn fi Ọgbẹni Oji Mmong ati iyawo rẹ, ti o njẹ Grace sun si ọjọ kẹdọgbọn oşu yi.

Nwọn fi a..ẹn t'ọkọ-t'aya mejeji sun ẹsun wipe nwọn ji oriş'riẹi ẹru ..gbẹni James Ihesiaka ko, ti aropo owo rẹ j. pọnun mẹta-le-lọgbọn a t i şile mọkanla (£33 - 11 - 0)

Nwọn n. awọn ko jẹbi.

Printed & Pubished by The Union Printing and Publishing Company., 28, Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370